# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KEJI, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**(ÌSÌN ỌRẸ ÀKỌ́SO)**

**OṢÙ KEJI, ỌDÚN 2023**

**MO DE AYÉ MI MỌ́ ORÍSUN ÀWỌN ÀMÌ ÀTI ÀRÀ ÀTÒKÈWÁ**

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8: am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

1. **Orísun igbàlà kíkún! Orísun igbàlà kíkún!**

Sí sílẹ̀ fún gbogbo wa,
Lát'Ọ̀dò Olùgbàlà wà,
Ló nṣàn yí gbogb'ayé ká;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

2. Ìran ológo li èyí

Ìsun ìwẹ̀nùmọ́ nṣàn,
Ó nwẹ gbogbo abàwọ́n nù,
Ti ìdálẹ́bi ẹsẹ̀,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ tí nwẹ̀ mọ́ láúláú.

3. Ìsun ijìnlẹ̀ ìfẹ́ Rẹ

Nṣàn ní inú ọkàn wa;
Ó nwẹ gbogbo erò aìmọ́,
K'a lè wà láílàbàwọ́n,

Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

4. Ìsun iyè aìnìpẹ̀kùn,
Láti ọ̀run nṣàn sí wa,
Ọlọ́run dàpọ̀ pẹ̀lú wa,
Idàpọ̀ t’ó dùn jùlọ;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

1. Ó ha lè jẹ́ pé mò n’pín
Nínú ẹ̀jẹ̀ Olùgbàlà?
P’ó kú fémi t’Ó dá lóró,
T’ó lépa Rẹ dójú ikú?
Ìfẹ́ ‘yanu! È há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

Ìfẹ́ ‘yanu! e há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

2. Ohun ‘ìjìnlẹ̀! Ọlọ́run kú!
Taní mọ ìdí ète Rẹ̀?
Lásán l’ángẹ́lì ta kọ́ da,
Nfẹ́ mọ, jìnlẹ̀ ìfẹ́ mímọ́!
Ànú ṣá ni! K’áyé júbà,
Kí ángẹ́lì ma wádì mọ́.
Ìfẹ́ ‘yanu! È há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?
3. O f’ìtẹ́ Bàbá Rẹ̀ sílẹ̀,

Ore-ọ̀fẹ́ Rẹ kò lópin!
Ó bọ́ gbogb’ ògo Rẹ̀ sílẹ̀,
Ó kú fún ‘ran ọmọ Ádám,
Ànú ṣá ni, láìní ìwọ̀n;
L’Ó wá mi rí, Ọlọ́run mi.

Ìfẹ́ ‘yanu! È há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

4. Ó pẹ́ ta ti de ẹ̀mí mi,
Ṣinṣin l’ó kun ẹ̀wọ̀n ẹ̀ṣẹ̀;
Ojú Rẹ́ tàn ‘mọ́lẹ̀ ìyè,
Mo tají, túbú sí mọ́lẹ̀;
Ẹ̀wọ̀n mí bó, mo d’omìnira.
Mo dìde, mo sì ntọ̀ lẹ́yìn.

Ìfẹ́ ‘yanu! È há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

## **Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo ìwo òkùnkùn tí wọ́n yàn láti tú ìfarahàn ògo mi ká l’ọ́dún yìí, kí n tó kúrò níyìn, ìwọ yóò kú, ní orúkọ Jésù.
2. Lónìí, nípa agbára tó nbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, èmi yóò gba gbogbo ibùkún tí mo sọnù ní àwọn ọdún tóti lọ padà, ní orúkọ Jésù.
3. Ohun rere ayé mi ìyówù ti wọ́n ti gbésin, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, ìwọ yóò gba ìyè lónìí, ní orúkọ Jésù.

4. Gbogbo ìhámọ́ra òkùnkùn tí wọ́n dojú rẹ̀ kọ idìde mi l'ọ́dún yìí yóò gbiná lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá mi àti Ọlọ́run mi, jẹ́ kí gbogbo ìdibàjẹ́ nínú ìgbé ayé ẹ̀mi mi gba agbára àjínde lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó pa Gòlíátì, Ọlọ́run mi yóò pa gbogbo ìjákulẹ̀ tí wọ́n ṣe lòdì sí ògo mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fa ire mú nínú ayé mi l'ọ́dùn yìí, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

### ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìwádì sátánì láti tú àtitẹ̀síwájú mi ká l'ọ́dún yìí, wó lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n rákórò lọ síbi ògo mi l'ọ́dún yìí, gbiná, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára òkùnkùn tí wọ́n gbà láti fòpin sí ayé mi l'ọ́dún yìí, pa àwọn tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ẹ̀rọ ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi l'ọ́dún yìí, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, k'osì pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí agbára olóríkunkun t'ówà nídi gbogbo iṣòro olóríkunkun nínú ayé mi, kí àṣírí rẹ tú, k'ósì gba itìjú lónìí, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**I Jòhánnù 2:14** Èmi kọ̀wé sí nyin, ẹ̀nyin bàbá, nítorítí ẹ̀nyin ti mọ̀ ẹnití ó wà lí àtètèkọ́ṣe. Èmi ti kọ̀wé sí nyin, ẹ̀nyin ọ̀dọ́mọkùnrin, nítorítí ẹ̀nyin lí agbára, tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sì dúró nínú nyín, tí ẹ sì ṣẹ́gun ẹni búburú ni.

**Orin Dáfídì 126:5** Àwọn tí nfi omijé fun ìrúgbìn yóò fi ayọ̀ ka.

**Orin Dáfídì 119:111** Ẹ̀rí Rẹ ni ogún mi láíláí: nítorí àwọn li ayọ̀ inú mi.

**Òwe 17:22** Inu-dídùn mú ìmúláradá rere wá: ṣùgbọ́n ibìnújẹ́ ọkàn mu egungun gbẹ.

**3 Jòhánnù 1:4** Èmi kò ní ayọ̀ tí ó pọ̀jù èyí lọ, kí èmi kí ó ma gbọ́ pé, àwọn ọmọ mi nrìn nínú òtítọ́.

**2 Kọ́ríntì 6:10** Bí ẹnití ó kún fún ibìnújẹ́, ṣùgbọ́n àwa nyọ̀ nígbàgbogbo; bí tálákà, ṣùgbọ́n àwa nsọ ọpọ̀lọpọ̀ di ọlọ́rọ̀; bí ẹnití kò ní nkan, ṣùgbọ́n àwa ní ohun gbogbo.

**Oníwàsú 9:7** Ma bá tìrẹ lọ, ma fi ayọ̀ jẹ oúnjẹ rẹ, kí o sì ma fi inú-dídùn mu ọtí-wáìnì rẹ: nítorípé Ọlọ́run tẹ́wọ́gba iṣẹ́ rẹ nísisìyí.

## <u>ÀDÚRÀ ṢÍWÁJÚ FÍFI ỌRẸ ÀKỌ́SO RẸ SÍLẸ̀</u>

**Na ọrẹ rẹ sókè, kí o sì gbàdúrà báyìí:**

“Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún fífún mi ní anfàní, okun àti ọgbọ́n láti ní ọrẹ irúgbìn yìí. Pẹ̀lú ọrẹ yi, mo dámọ̀, mo si yìn Ọ́ gẹ́gẹ́ bí orísun kànṣoṣo

ti ìṣúná mi. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ nítorí nígbà kan rí mo ti sọnù, ṣùgbọ́n a ti ṣàwárí mi báyìí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún igbàlà ọkàn mi.

Bí mo ti n fi ọrẹ àkọ́so yì sílẹ̀ báyìí, tẹwọgbà á , Olúwa, nípa agbára tó nbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Nípa ọrẹ yìí, mo jẹ́wọ́ wí pé, Ìwọ ni olú àníyàn mi. Ọlọ́run, dìde, kí o si lo ọrẹ yì gẹ́gẹ́ bí kọ́kọ́rọ́ sí ipọ̀si, títóbi, ìgbéga àti ojúrere mi tíkò wọ́pọ̀. Nípa ọrẹ yìí, jẹ́ kí gbogbo agbára afinisọ̀fò gba ìparun kúrò nínú ayé mi. Gbà mí kúrò nínú àdánù yòówù, kí O sì fi àwọn ibùkún tí owó k'òlè è rà gbé ayé mi wọ̀.

Nípa ọrẹ yìí, mo so ara mi pọ̀mọ́ orísun ètò ìṣúná owó ti ọ̀run tó ṣí sílẹ̀, alàjá tíkòwọ́pọ̀, ìṣerere tó n jẹgàba, ojúrere tíkòwọ́pọ̀, aṣèyọrí tó tayọ eròngbà àti ìṣẹ́gun pátápátá, ní orúkọ Jésù.

Bí mo ṣe n fi ọrẹ àkọ́so yìí sílẹ̀, jẹ́ kí agbára iyàsì-mímọ́ rẹ ṣàn sínú àwọn ètò iṣùná mí tókù. Olúwa, gbé mi wọ inú ibi, ipò, ifòròróyàn àti ọgbọ́n àtòkèwá Rẹ fún ayé mi. Jẹ́ kí wàrà àti oyin ilẹ̀ yìí dí gbígbìn si óókan-ayà mi.

Èyí ní mo gbàdúrà, ní orúkọ nlá Jésù Kristì Olúwa. Àmín."